# “Ki n sọ pe: Subhaanallah, wal hamdulillah, wa laa ilaaha illallohu, wallohu akbar, jẹ nnkan ti mọ nifẹẹ sí ju nnkan ti oorun ran le lori lọ”

Lati ọdọ Abu Hurairah, ki Ọlọhun yọnu si i, o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, sọ pe: “Ki n sọ pe: Subhaanallah, wal hamdulillah, wa laa ilaaha illallohu, wallohu akbar, jẹ nnkan ti mọ nifẹẹ sí ju nnkan ti oorun ran le lori lọ”.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe dajudaju riranti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- pẹlu awọn gbolohun ti wọn tobi yii loore ju aye ati nnkan ti o wa ninu rẹ lọ, awọn naa ni: “Subhaanallah”: Afọmọ ni fun Ọlọhun kuro nibi awọn adinku. “Alhamdulillah”: Ẹyin ni fun Un pẹlu awọn iroyin pipe pẹlu nini ifẹ Rẹ ati gbigbe E tobi. “Laa ilaaha illallohu”: ko si ẹni ti a le maa jọsin fun pẹlu ẹtọ afi Ọlọhun. “Allahu Akbar”: Ẹni ti O tobi julọ ti O gbọnngbọn ju gbogbo nnkan lọ.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/6211